William R. Bascom
Northwestern University

William Bascom, Director
Museum of Anthropology
University of California
Berkeley 4, California

BASCOM

# IWE ITAN

BI

# ALUKURANI

***TI ṢE BẸRẸ NI ILU MẸKA***

ATI

## ITAN IGBE-AIYE MUHAMAD

*LATI ỌWỌ*

*Ọgbẹni* **E. A. AKINTAN**
*Principal, Lagos Public School.*

*Adedimeta Press, 183 Bamgbose Street Lagos.*

# AWON ORO AKOSO

Mo kọ iwe kekere yi fun anfani awọn enia wa ti nwọn ko ni anfani ati ka iwe ede Gẹsi lati mọ bi iwe Alukurani ti ṣe bẹrẹ, nipa ẹniti o kọ ọ, akoko ti nwọn kọ ọ, nipa awọn ohun ti o wa ninu rẹ, ati ọpọlọpọ ohun miran ti o jẹ mọ iwe na.

Iwe yi pin si Apa Meji: Apa Kini (Part 1) kun fun (1) Kini Alukurani jasi, (2) Tani kọ ọ, (3) Akoko ti nwọn kọ Alukurani, (4) Awọn eto Alukurani lẹsẹsẹ, (5) Alukurani ti isisiyi pẹlu eyi ti Muhamad palaṣẹ fun lilo, (6) Kini awọn ohun pataki ti o wa ninu Alukurani, (7) Aṣaro Kukuru lori itan igbe-aiye Muhamad ẹni ti o sọrọ inu Alukurani. Apa Keji (Part II) kun fun awọn aṣayan ẹsẹ Sura lati inu Alukurani lati ibẹrẹ iṣẹ iwasu Muhamad ni Mẹka titi o fi de Medina lati fihan pe bi igbe-aiye Muhamad ti nlọ si bẹni nwọn fi nkọ awọn ọrọ ti o wa ninu Alukurani. Bi mo ti nla alaye ọrọ kan bẹni mo nfi ẹsẹ tabi aya Alukurani kọkan silẹ lati ṣe atilẹhin fun awọn ọrọ ti mo nsọ.

Mo dupẹ gidigidi lọwọ awọn ẹniti o kọ awọn Iwe wọn yi ti mo lo. Awọn iwe na ni wọn yi:—"The Life of Muhamad," "The Historical Development of the Koran," Outlines of Islam," awọn mẹtẹta lati ọwọ Ẹni-Ọwọ Canon Sell, D.D., Iwe Alukurani lati ọwọ Ẹni-Ọwọ M. S. Cole, M.A., L.Th., "The Koran in Islam," lati ọwọ Ẹni-Ọwọ W. Goldsack, "The Islamic Faith," lati ọwọ Ọlọla Sir Thomas Arnold, "The Koran," lati ọwọ Ọgbẹni George Sale, "Christianity and Islam," "The Bible and the Koran," lati ọwọ Ẹni-Ọwọ W.R.W. Stephens," "A Short History of the World," lati ọwọ Ọgbẹni H. G. Wells, ati "The Story of the Bible" lati ọwọ Ọgbẹni Macleod Yearsley.

Ireti mi ni pe iwe kekere yi yio jẹ ohun ilaju fun ọpọlọpọ awọn enia lọmọde lagba ti o nfẹ mọ bi iwe Alukurani ti jasi.

**E. A. AKINTAN**
*Principal, Lagos Public School.*

71, Oshodi Street,
Ẹpẹtẹdo,
Lagos
Feb. 1942.

## Other Publications by the same Authors

1. *Training in English* ... ... ... ... 1/-
2. *Iwe Ede Gẹsi Olohun Iyọ Part I & Part II at 3d. each, and Part III 6d. each.*
3. *Lectures on Astronomy (a) Solar System 6d. each*
   *(b) Stella System 6d. each.*
4. *First Steps in Yoruba Composition .... 6d. each.*
5. *Second Steps in Yoruba Composition in print.*